To the Chief Secretary to the Govt

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 278. SATURDAY, JUNE 9, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silẹ.

NIGERIAN SECRETARIAT 15 JUN 1928

Akin Adesigbin


SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Medicine Dealers
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and
Soreness after
Severe Exertion
General Directions
for External Use
away from
flame
LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
DrEarlSloan
TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### IDA 'LU NI ŞE 'LU.

Ẹrin kekere kọ lo pa wa ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ to kọja nigbati a ri awọn Kurumọ obinrin bi mẹwa kan pẹlu ọkan ti o şiwaju wọn ti o si ngbe ara fo soke bi *rubber* ti o fo fẹrẹ bi afegboludo, ti nwọn si nkọrin kakiri odo Oluşi ati adugbo miran, nigbati a si bere pe pantiwa ede Ẹyọ, bẹni a sọ fun ni pe nitori ẹnikan ninu wọn mu ọbọ, o si yege pe on ki şe aje lo mu ayọ bẹ wa, ẹniti o si yege ogun yi ni Kurumọ obinrin ti a sọ fun ni pe on lo şiwaju awọn ẹgbẹ rẹ to ku ti nwọn npatẹwọ kiri fun biba ẹnikeji wọn yọ.

### L'OFEREFE, L'OFEREFE, ỌKỌ ONIDAN L'OFEREFE.

Gbukẹ ni a ri ọkọ ofurufu miran ti o wa bẹ ibi wo ni ọsan Satide to kọja, kikun rẹ bi ọlọbọnunbọnun lo mu pupọ tajukan wo oju orun ti nwọn si ri ọkọ onidan yi bi o ti nfo lọ lokeloke bi ẹiyẹ, nikẹhin ni o lọ sọlẹ si ọdan: nibiti ẹgbagbeje enia rọ lọ wo; ọkọ Faranse ni eyi, a si sọ pe lati ilu Kutọnu lo ti wa: irisi rẹ dabi agan bọ ti o gun, o ni'nu; iyẹ rẹ si dabi ti labalaba.

### IYAWO TO LARINKIN.

Ọgbẹni J. B. Adejokun, Ọga Ile-iwe Tinubu School gbe Om'dan kan awẹlẹwa niyawo ni *Church Breadfruit* ni ọjọ kejilelogun oşu to kọja.

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### IYI PADA ỌJỌ.

Nigbagbogbo li a ma nwoye iyipada ọjọ, eyiti o yẹ fun wa lati ma mọ gẹgẹ bi o ti ni lati ma lọ si.

Ni igba miran ọsan a gun ju oru lọ, ni igba miran ẹwẹ oru a gun ju ọsan lọ, bayi ni ọjọ ti ma nlọ si, şugbọn ni sa yi agogo mẹfa owurọ ni ofe nka orun si nyọ ni iwọn agogo meje ku işẹju mẹdogun, dipo agogo mẹfa kọja işẹju mẹdogun ti ilẹ ni lati mọ ati pẹlu dipo agogo meje gan ti orun ni lati yọ—orun si nwọ ni agogo meje alẹ nisisiyi eyi fihan wipe ọsan gun ju oru lọ.

### ALAKORO SQUARE ATI CAMPOS SQUARE.

Iba dara julọ bi awọn Alabojuto Ọlọpa *Superintendent of Police* ba le yan awọn Opa-Ọba si awọn Gbangba meji ti a darukọ wọnyi fun abojuto ewu awọn mọtọ; gẹgẹ bi o ti jẹ wipe ọpọlọpọ igba ni a ma nşe a fiyesi dida lamu ti awọn mọtọ wọnyi nda awọn enia lamu nibẹ nigbati mọtọ ba fẹ kọja larin wọn, ko yẹ ki jamba kan şẹşẹ şe ẹnikan ki a to ri wipe o yẹ ki a şe gẹgẹ bi a fiyesi wa yi,

### ILẸ ITA OKE-ARIN.

Ẹniti o ba de Oke-Arin nisisiyi ni ibiti awọn (Town Council) gbe fi Busọ si, yio ri wipe ibẹ ko yẹ ni ipo ti ọmọ enia le duro si lati şe ohunkoun arara; gẹgẹ bi o ti jẹ wipe owo ni awọn ẹniti o nta ọja ni Busọ wọnyi nsan ati fun alafia ilu; iba dara bi awọn (Town Council) ba le yẹ ilẹ ita Oke-Arin wo, ki nwọn si tun ibẹ şe gẹgẹbi o ti tọ nitori ojo ko jẹ ki nwọn gbadun aye na to bẹ—eyi yi si ni igbe pataki ti a nke nigbati awọn (Town Council) ndaba Buşọ Oke-Arin na lọjọ kinni.

### SAMANI OJO.

Samani ojo li a wa yi, ọpọlọpọ ile ti orule rẹ ko lagbara lo nko wahala ba awọn enia, eyi si nmu ki a ma ri wọn loke ile wọn firifiri—ki Ọlọrun bo aşiri gbogbo ẹniti orule ile wọn ko le, lati tun wọn şe.

## LAGOS TOWN COUNCIL.

A ngbọ wipe ọpọlọpọ ẹrọ omi-iju ni ko wulo fun lilo awọn enia ni ilu eyi si mu ki awọn enia ma jijakadi ni idi ẹrọ omi-iju nigbati nwọn ba ju mẹrin lọ ti nwọn ni lati pọn omi ti o si jẹ wipe ninu oju mẹrin ti o wa fun ẹrọ omi-iju yi lati lo, agbarakaka ni nwọn fi nri oju kan tabi meji lo—nitorina a bẹ ẹnyin Munisiba ki ẹ fi yesi titun awọn ẹrọ omi wọnyi ṣe fun awọn enia, nitori ijowo ni ki iṣe ijọfẹ.

## AGBO LO ṢORO LỌJỌ ILEYA.

Bi nwọn ti ndari bọ Mọṣalaṣi ọdun lọjọ Alaruba ti o kọja bẹni a gbọ wipe awọn meji kan pade ara wọn lapa Ọbun Eko ni nwọn si mbere bi ẹran agbo kan ti o sọnu ti ṣe rin lọwọ ara wọn iyoku iregbe nwọn ni nwọn ko ritiriti ọran na o di iwaju awọn agbagba ti ngba ara ilu ni Ebute Ero—igi ma da o!

## ỌMỌ-JAGUDA.

A gbọ pe awọn ọmọ Jaguda nba awọn ero ti o nlọ si idalẹ wọ mọtọ pọ ni ero lati ṣe jamba: Ni iwọn ọsẹ kan sẹhin ni nwọn ra ọkan mu ninu mọtọ lati de Agenge; ki la ti ma ṣe ti awọn ọmọ Jaguda wọnyi si?

## AWỌN OBINRIN IMALE.

Ni aseko ọdun Ileya bayi, bi enia fi Ọlọrun bẹ wọn, nwọn ko jẹ kọ ọko wọn silẹ, nigbati Adukẹ Salamọtu tabi Ibadiaran ba ngbara ẹhin-ẹran dindin ti gbogbo rẹ nṣe ṣin-ṣin-ṣin ninu iṣasun ti awọn na a ma gee ti nwọn a ma sọ-kai nwọn gbadun ẹran-Ileya de aye kan.

## ENMỌ NLA!

A gbọ wipe ogbonkangi ọkunrin kan bọ ara rẹ silẹ kombo ni ihoho ọmọ-luwabi ni adugbo Massey Street, ni owurọ ọjọ Alamisi 31/5/28; bayi ni ọkunrin na si bẹrẹ si pa kọkọko lati ko wole onile eyi jẹ inira pataki fun ilu; nigbati o si tun di alẹ ọjọ kanna yi ni nwọn tun ri ọkunrin kan ni Ricca Street, ni dede agogo mọkanla oru, ti eyi papa si ndi alafia awọn ara adugbo na lọwọ—abẹ awọn Ọlọpa o tọ wipe ki nwọn tete ma kọ ibi ara si irufẹ awọn janduku enia bawọnyi ni arin ilu lati ma mu wọn yẹra kuro nitoripe nwọn nyọ ilu lẹnu ni.

## HOLLOWAY STREET.

Adugbo yi bajẹ pupọ debi ti ko fun enia ni anfani lati kọja ati pẹlu papa fun awọn ara adugbo yi, adugbo kan ko yẹ ki o wa ni irufẹ ipo ti o wa, a fi eyi han awọn (Lagos Town Council) ki nwọn jowọ nitori ilera ilu ki nwọn dide laipẹ yi lati ri si didabo bo adugbo na fun alafia.

## GASA IKU NLA!

Gbukẹ li a gbọ wipe ọkunrin kan ku lọjọ Alamsi 31/5/28, eyi ti nwọn sọ wipe o yọ ẹjẹ lẹnu ati ni imu, nigbati Asarayilu mu u; irufẹ iku bẹ apẹrẹ lo jẹ fun ọmọ Anabi Adamọ—ki Sati ma ṣọ ni lọwọ orişirişi jamba iku.

## ORO KANGI KAN.

A gbọ wipe ọmọkunrin kan ba Egungun kan wọ 'ya ija lapa horo kan ni ọjọ Jimọ ijẹsan ti nṣe ọjọ kini oṣu yi—o ro kangi kan lo d'ifa fun ẹniti o nlọ si ode-awo, nwọn ni ki o rubọ ijakadi ki o ma ba kan "o ro kangi kan" o kọ ko ru u.

## JIMỌ-ỌDUN.

Ni ọjọ kini oṣu yi—ọjọ Jimọ ni awọn Musulumi Jamat-ilu ati awọn Imale ṣe Jimọ-ọdun, gẹgẹ bi Jimọ ọdun na ti sunmọ igbati nwọn kirun papa eyi mu ki gbogbo rẹ tubọ dun yungba bi oyin, olukuluku wọn ṣe ẹṣọ rẹpẹtẹ bi eyiti ayọ mbọ—adura ti wa nipe ki Ọlọrun jẹ ki ilu o dun lẹhin ọdun Ileya yi, amin-aṣẹ ṣiṣẹ-ṣiṣẹ ni ti lakọṣẹ.

Bi ọjọ Jimọ yi ti dun to ni Mọṣalaṣi Jimọ bẹni ero pọ lọ sua bi omi a ko le ṣẹṣẹ ka awọn ero iworan ti nwọn wa wo bi Jamat-ilu yio ti dabira si—anu ṣe wa diẹ lati gbọ finrin bi ẹnipe awọn olori ma ni fila kan takanrangbọn si ilu lojude Mọṣalaṣi nla na ni ireti pe Jamat yio tu 'tọ si oke lati fi oju gba nwọn o si mọ wipe ankori Magani Duniyan ọjọ kini ni Jamat fi nṣẹgun ti nwọn si fi ntẹdi alaṣeju bọ'mi gbigbona. A ki Lemọmu Ligali ati gbogbo Jamat ẹmi a lọra o, ki Ọlọrun si ṣe ọdun na ni abo ọdun ki alafia ka ri ile kowa.—Amin

## ENMỌ DE!

Otitọ ha ni iro ti a ngbọ yi firifiri pe awọn kan nda 'na kakiri oko ni Oke-odo titi lọ de awọn ọna Agege ti nwọn si nṣe jamba fun awọn enia tobẹ ti nwọn fi sọ wipe bi ẹnikan tabi meji ba ṣeṣi lọ rin bi ọwọ awọn ipata Danadana yi ba tẹ wọn pipa ni nwọn ma pa wọn? ti eyi ba jẹ gẹsikiya hanun o tọ o si yẹ wipe ki awọn olori Ọlọpa tokere da awọn "arabi" si ode; igbona-igboru lanj' ọpọlọ o!!

## AJABA INA.

Ina to jo ni oru ọjọ Jimọ mọjumọ ọjọ Satide ijẹjọ ni Oke-Arin jo kabari irufẹ ina bẹ li a le fi we ina Idunmọta tabi ti agbo-malu ati ti ina Hotẹnu ni igba lailai, bi ko ba si ti awọn panapana Ijọba ati awọn oyinbo gbogbo bi ẹgba a gbe ẹ ti a gbọ wipe o ṣiṣẹ sibẹ bi a ti nsọ yi ko ni a ma sọ o.

Eşi ni irufẹ ina bẹ jo ni Oke-Arin a ko si tanma pe Ijọba ti fun wọn ni aye lati igba na lati kọ ile wọn pada: Awọn enia mẹjọ tabi ju bẹ lọ ni nwọn sọ wipe o ba ina ijẹjọ rin ninu awọn ti nwọn wi nwọn sọ wipe ọmọ-iya mẹta mbẹ ninu wọn nwọn si sọ wipe awọn kan farapa tobẹ ti nwọn fi ru wọn lọ si ile Alarun—gbanmọ-gbanmọ ina ribiti-ribiti bayi ni Oke-Arin ko yẹ wa: a ki gbogbo awọn ara adugbo yi nwọn nku ewu, ki Oluwa si fi ofo ra ẹmi awọn ẹniti "Ajaiba ina"

ti o le ṣe. Lọna yi, eyi le fun olukuluku enia ni okun si, a si tubọ mu ni ni igbagbọ pe a le ṣe gudugudu meje. Ẹniti o kere tabi ti o rẹlẹ ju le gba fun ẹlomiran, o le ni ireti, o si le ni igboya, ani niwaju awọn ẹni nla julọ.

Awọn ara wa, awọn ẹni nla wonyi—awọn ẹjẹ ati itan wa, awọn ẹni gbogbo aiye, nwọn ṣi nba wa soro sibẹ lati inu iboji wọn, nwọn si nke si wa ki a tọ ọna kanna eyiti awọn na ti tọ. Apẹrẹ wọn wa pẹlu wa sibẹ lati tọ wa, lati kọ wa ati lati fi ọna han wa. Nitori ogun ajẹbọwaba ni iwa ọmọluwabi jẹ, a wa lati iran de iran, a si ma se ati parọ ara rẹ firifiri.

Awọn Chinese ni "ọlọgbọn ni iṣe olukọ awọn iran kan de ọgọrun iran. Nigbati a ba nsọ ti iwa Loo, ọpe enia a di oloye, ọjọ enia a si di akin." Bayi ni a ri pe iwa ti enia rere kan hu jẹ ihin-rere ti gbefe ati ti idasilẹ fun gbogbo awọn ti nbọ lẹhin rẹ: "Bi awọn ti a fi silẹ ko ba gbagbe ẹni, a ko ku."

Awọn ọrọ ọgbọn ti awọn ẹni rere ti sọ, apẹrẹ ti nwọn ti fi lelẹ, ki ipare lai; iwọnyi a di ero ati iwa awọn ti o rọpo wọn, nwọn a jẹ iranlọwọ fun wọn nigba aiye wọn, nigba pupọ iwọnyi a si jẹ itunu fun wọn nigbati akoko iku ba de.

Henry Marten ẹniti o ku ninu ẹwọn, ọkan ninu awọn oṣelu ni aiye Cromwell sọ pe "Iku ti o buru ju tabi iku gbigbona julọ ko jamọ ohun kan lẹgbẹ iranti pe oluwarẹ lo aiye rere; ẹniti o ba si ni anfani nlanla lati fi ẹkọ ati apẹrẹ irufẹ eyi lelẹ fun awọn ti o nbọ lẹhin, oluwarẹ nikan ni iṣe ẹni nla!"

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### Departues.

By the R.M.M.L. *Apapa* which sailed this port on Friday the 1st June, 1928, His Honour Justice M. L. Tew, His Lordship the Bishop of Lagos, F. Melville Jones and Mrs. Jones, Dr. T. B. Adam, Mr. Robert. F. Irving, B.L., and Mrs. Irving, Mr. C. N. Pearson, Government Dental Surgeon and Mrs. Pearson, were among the passengers to Plymouth.

### Birthday Honours, 3rd June, 1928.

WEST AFRICAN LIST.

C.M.G.—Mr. Cyril Wilson Alexander, Resident, Administrative Service, Nigeria; Major Arthur Heney Chamberlain Walter-Leigh, Chief Commissioner, Northern Territories, Gold Coast.

---

C.B.E.—William Bowden, Provincial Commissioner, Sierra Leone; George John Frederick Tomlinson, Formerly Assistant Secretary for Native Affairs (Retired) Administrative Service, Nigeria.

---

O.B.E.—William Frederick Becker, District Manager, for Nigeria, Bank of British West Africa Limited, and Member representing Banking in the Legislative Council, Nigeria; Duncan Elliot, Executive Engeneer, Public Works Department, Nigeria.

---

M.B.E.—T. O' Baka Torto, African Assistant Treasurer, Nigerian Treasury Department.

---

KNIGHTHOOD—Hon. Kitoyi Ajasa, O.B.E., Barrister-at-Law, Senior African Unofficial Member, Legislative Council, Nigeria. Congratulations.

### Births.

Mrs. Comfort Roberts wife of Mr. J. S. Roberts of 10, Baban Street, Ebute Metta, was delivered of a female child at Massey Dispensary, Lagos, on Saturday morning, the 2nd June, 1928 at 6.55 a.m.

It is reported that both mother and child are doing well. Congratulation.

And Madam Lucy Ibidunni Orioye, wife of Mr. Popoola Oderinde, Cashier of the Barclays Bank, Lagos, of a female child on Monday Morning the 4th June, 1928. We understand that both Mother and baby girl are doing well. Ki Olorwa ko da awon omo meji yi si. Congratulation.

### Wedding Bells.

The marriage took place at St. Jude's Church, Ebute Metta, on Tuesday the 5th instant, at 10.30 a.m., between Mr. James Ladipo Kasumu, Junior Bailiff, Supreme Court, Lagos, and Miss Solabomi Adebola, daughter of Mr. Jonathan Coker, [Pensioner], and Farmer, and brother of J. K. Coker, Esq., of Lagos and Agege.

The ceremony was performed by Rev. James Jameison Pearse, LTH., assisted by Rev. W. O. Aiyedun, B.A.

We wish the Bride and Bridegroom long life and happy home.

### J. H. Doherty *versus* Wusamotu Shele.

Judgment was entered for late J. H. Doherty of Campos Square, Lagos, against his wife Madam Wusamotu Shele for the sum of £7,671 with costs, to be taxed, by Mr. Justice M. L. Tew.

Counsel for the Plaintiff—Mr. J. T. Nelson-Cole and Mr. Adedapo Kayode.

Counsel for the Defendant—Hon. E. O. Moore, Messrs Mobolaji Akishemoyin and Alakija and Alakija.

### Death of Mr. Abraham Macaulay.

The death is announced with deep regret of Mr. Abraham Macaulay of 52, Olókodana Street, Ebute Metta, on Thursday morning, the 24th May, 1928, at 4 a.m.

The funeral service took place the same afternoon at United Native African Christ Church, Ebute Metta, at

3.30 p.m., before a large concourse of people. Rev. E. Ayo Sala officiated. And from thence to Yaba Cemetery for interment.

The late Mr. Macaulay was a good christian, kind and gentle; lost his wife in the year 1917

To his only surviving son Mr. Emanuel A. Macaulay and to the relatives of the deceased, our condolence—Aged 68. R.I.P.

**Ah ! What is man.**

The death took place of Mr. Ezekiel Bankole Dada, 1st Class Clerk, Audit Department Ebute Metta. at his residence 22, Offin Road, Lagos, on Saturday evening, the 2nd June, 1928.

His remains were removed to Wesleyan Ereko Church, at 3.30. p.m. on Sunday afternoon the 3rd instant Revs. A. N. Cole, T. J Henry and M. O. Dada officiated, and to Ikoyi Cemetery for interment.

Mr. Dada was an exemplary Christian, a staunch member of Ereko Church, Lay Reader, and a Steward Circuit.

The deceased was a quiet going man and very unassuming.

To his widow, children and the rest family of the deceased, our profound sorrow.

May his soul rest in peace.

**Obituary.**—Mr. Isaac Thomas of the Lagos Town Council Office, on the 7th June, 1928, at the African Hospital.

OLUSAKIN.

## Government Notices.

No. 120 ]

His Majesty the King has been graciously pleased to make the following appointments :—

To be a Knight Bachelor —

Mr Kitoyi Ajasa, O.B.E.

To be a Companion of the Most Distinguished Order of Saint Michael and Saint George :—

Mr. Cyril Wilson Alexander.

To be a Commander in the Civil Division of the Most Excellent Order of the British Empire :—

Mr. George John Frederick Tomlinson.

To be Officers in the Civil Division of the Most Excellent Order of the British Empire :—

Mr. William Frederick Becker.

Mr. Duncan Elliott.

To be a Member of the Civil Division of the Most Excellent Order of the British Empire :—

Mr. James Godfrey Tetteh O'Baka Torto.

PAGIDARI.

Ogbẹni Isaac B. Thomas ti Munisipa jẹ alaisi ni Thursday osẹ yi ti ṣe ọjọ keje oṣu yi, ni *African Hospital*, l'Eko.

A ba awọn ẹbi ati Ibatan Olõgbe kẹdun iku rẹ: ki Ọlọrun gbe si afẹfẹ rere.

## Rest in Peace.

It is with the deepest regret we record the death of Mr. Isaac B. Thomas Building Inspector of the Lagos Town Council which sad occurrence took place at African Hospital on Thursday the 7th instant our sympathy to the bereaved families.


INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, JUNE 9, 1928.

## KITOYI?

Ẹnikẹni ti o ba dẹ oju silẹ ki o ri imu yio ri gbangba pe Eko ode oni kuro ni Eko jẹlẹnkẹ bi o tilẹ jẹ pe aimọye nkan lo nfarahan pe igbadun ti o ni lari mbẹ ninu rẹ.

Ni koi ti pẹ ju yi ni a tun ngbọ pe oku miran ti o ba ku tun di gbigbe digbadigba bi ẹniti o ngbe apo ekurọ ni Idọhọ, lọ si ile lakulaku ni apa Ikoyi eyi fihan gedegbe pe arun ṣi wa ni ilu bi awọn Ijọba ti nṣe itọju Eko to yi, kini awọn Wolewole wa fun? Kini awọn Fọlefọle wa fun? Ani kini ogidinleje awọn Dokita Ọba wa fun? Bikoṣe fun pe ki ilu le ni irọra ati alafia. Ṣugbọn o ha ri bẹ bi? Ẹ boju wo bi nkan ti ri ni igboro ilẹ yi loni, oriṣirişi aluba ni a ngbọ pe o nṣẹlẹ, ki ẹlomiran mọ mọ ṣe "onikọ iku" ara rẹ, ki ẹlomiran ṣalabapade agbako ni ọna abami; bayi ni a ri pe gbogbo nkan nlọ lodilodi nisisiyi, a le bere kilo mu eyi wa? Ọda owo, ọda iṣẹ, airi onjẹ jẹ, airi ile gbe jẹ diẹ ninu awọn ohun ti o nmu inira ba pupọ ninu awọn ara ilu: ninu eyiti a nwi yi ni a gbọ pe ni *Wednesday* ọsẹ yi ni iwọn agogo mẹwa arọ, awọn ọmọ Kiriyo meji-mẹta kan mu owo diẹ lọ ba Gambari kan ta tẹtẹ ni ireti pe boya nwọn le sọ õkan ẽji ti nwọn mu lọ na di ẹta: ṣugbọn ki la ri, a sọ pe kete bi nwọn ti bẹrẹ "iṣẹ" awuruju yi, lọgan ko gba Gambari na ni iṣẹju pupo ki o to fi owo awọn ọmọ Kiriyo na lanu, bi igbati ologbo iba fi ekute lanu; kia ni awọn ọdọmọdekọnrin na ṣiyan ti nwọn ko si duro gb'ọbẹ; ẹnyin na ti gbagbe igbati a gbọ pe ẹnikan ri ọmọ jojolo ẹjẹ ọrun kan he ni apa *Sandgrouse* ti o si di ti Ijọba? Gbogbo nkan wọnyi lo mu ni bere Kitoyi? Nijọ wo ni gbogbo segesege wọnyi ma yi pada? Ẹ tun wo ọdun Ileya ọdunni ki a mu ti ọjọ ti awọn Janma lọ si Mọṣalaṣi lọ kirun kuro ati ọjọ bi meji-mẹta lẹhinna, ẹniti o ba woye yio kiyesi pe ilu ko tu gbugbu, ki a si ma ri awọn ọlọdun yẹ̃ yẹ̃ yẹ̃ nihin lọhun; kilo mu eyi wa, bikoṣe aidun-inu ọpọlọpọ, ode ko jẹun: ẹlomiran ti boya ibatan rẹ wa ni ihamọ tabi ti o ku iku ojiji, tabi ti lasigbo aiye ti kọlu, kọ ni yio wipe on raye *fry* ara ki on si ma gbe ọdun kakiri igboro, lẹhin igbati o ba ti lọ kirun, ti o ba si ti le jaja pa ẹran, ki o si ha tan; orule b'aja mọlẹ, aṣọ bo 'ṣe idi ni bi nkan ti wa si fun ọpọ enia nisisiyi. Ẹ tun wo ajalu ina oku ma jẹ 'lẹ o mọ ti o jo ni Satide to kọja ni Oke Arin, ninu eyiti a gbọ pe awọn bi mẹfa tabi jubẹ lọ lo bã rin, a le ṣẹṣẹ tun le ma fẹnu sọ ofo nlanla ti awọn enia bi Ọgbẹni Alli Sanni, Alhaji Mustafa, Ọgbẹni Jacob Cole, Ọgbẹni David Ajọsẹ ati awọn jakanjakan miran ṣe, ẹnikẹni ti o ba digbẹrẹ lọ si ibi ti ina na ṣẹ, ko ni ṣai f'ọwọ m'ori nigbati oluwarẹ ba ri bi a ti nko awọn enia ti ina jo pa, ti ara wọn si bo boro, ti o funfun bi ara ẹlẹdẹ!!! eşi ti ina kan ma ṣẹlẹ nibẹ ni yi, ki a si tun gbọ pe adugbo kanna yi ni ina tun ṣẹ lọdunni, kitoyi? Gbogbo nkan wọnyi ṣe ni loju sũ, a ko si mọ orin ti a le kọ sĩ, bikoṣe ero ya wa wo!

Iṣẹ etutu si ilu ti o ti jẹ ohun ti awọn agbagba ti nṣe ri, ko si mọ; bi o ti tọ ko si mọ, bi o ti gba le ku, njẹ bayi ni awọn agbagba ode Eko oni yio dakẹ lalai wa wọrọkọ fi ṣ'ada lati ṣe etutu ti o tọ si ilu? Ko ma si ilu ti ko ni ọna etutu tirẹ, awọn Oyinbo ni, awọn jakanjakan miran ni, Eko ko ha ni nkan etutu tirẹ ni ọna ọpọlọpọ bi? Ko se alaini, ṣugbọn loni nkọ?

A! òbìrì aiye pada,
Onisango d'Ọlọya!!!

---

## ỌJỌ IBI ỌBA JỌJI KARUN, GEORGE V.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU. ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Ọjọ mẹta li o jẹ pataki fun enia li aiye.

1. Ọjọ Ibimọ.
2. Ọjọ Igbeyawo.
3. Ọjọ Iku.

Ṣugbọn eyiti o jẹ pataki julọ ninu mẹtẹta ni Ọjọ Ibi; nitori ẹniti a ko bi ko le de aiye, ẹniti ko si li aiye ko le gbe Iyawo, ẹniti ko si de aiye ri ko le ku.

Ọjọ Iku, ọjọ ẹkun on ọfọ ni; Ọjọ Igbeyawo, ọjọ ayọ ni; ṣugbọn bi Iyawo na ba jẹ agbere ati alakowaba obinrin, ọjọ ti ọkọ re gbe e sile di ọjọ abamọ; ṣugbọn Ọjọ Ibimọ, ọjọ inu-didun papa ni; ibi ti o mọ li o njẹ ọmọ.

Ni ijarun, June 3rd, li o di ọdun ketale-lọgọta ti a bi Ọba wa Ilu Gẹsi, King George V. lati ọwọ iya rẹ, Ayaba Queen Alexandria. Ọba Jọji ni ọmọkunrin keji ti Ologbe King Edward VII, baba rẹ bi, nitori Ologbe Duke of Clarence ti o ku ni ọdun kejile-lọgbọn (1892) jẹ ẹgbọn rẹ.

Nigbati o di ọmọ ọdun mejila, ni ọdun kẹtadi-ladọta (1877) ni Jọji bẹrẹ si kọ iṣẹ (Cadet) ninu ọkọ omi kan ti a npe ni Britannia, o si wa nibẹ fun ọdun meji. Lẹhin na ni on pẹlu Ologbe ẹgbọn rẹ wọ Ọkọ ti a npe ni Bacehante kiri aiye fun odidi ọdun mẹta gbako.

Lẹhin na, ni o jẹ oye ti a npe ni Midshipman ninu Ọkọ Canada li ọdun kọkanle-logoji; o gba oye Lieutenant ni ọdun kankandi-logoji, o si gba oye Commander ninu Ọkọ-ogun kan ti a npe ni Thrush ni ọdun kẹrinle-lọgbọn.

O gbe ibatan rẹ, Princess Mary ni Iyawo ni ọdun kọkanle-lọgbọn. Ọdun mẹjọ lẹhin na, on pẹlu Iyawo rẹ gba ategun kiri Ilu, nwọn si jọ lọ si Ilu India ni ọdun kọkandi-logun.

Jọji, Ọba wa ti o wa li ori oye nisisiyi, ko mọ wipe on le jẹ Ọba lailai, nitori iya baba rẹ, Queen Victoria, alanu, ẹni rere ati ololọ enia pe li ori oye pupọ, o si jẹ Ọba fun odidi ọdun mẹrinle-lọgọta (64 years) 1837-1901. O bi ọmọkunrin mẹrin ati ọmọbinrin marun. Li akoko rẹ, aiye r'oju, aiye toro. Awọn Oyinbo igbana, ẹru Ọlọrun ni nwọn.

Ọba obinrin yi ku ni ọdun kẹtale-logun (1901) Dawodu ọmọ rẹ, King Edward VII, si rọ ipo rẹ. Ọba yi kẹrira ija, o si fẹran alafia tobẹ gẹ, ti a fi npe e ni "Eward the Peace Maker." O wọ aja ni ọdun kẹrinla, (1910.)

Dawodu rẹ okunrin, Duke of Clarence, ti ku ki on papa to jẹ Ọba, eyi li o fun aburo rẹ, Ọba wa Jọji li aye ati rọ ipo rẹ; o si gba ade li ọdun kẹtala, (June 21st, 1911.) Ọdun keji lẹhin na, ni on pẹlu Iyawo rẹ lọ si Ilu Jamani (German), li ako o ti aburo rẹ, Princess Victoria Luise, arẹmọ-obinrin Kaiser ẹgbọn rẹ, ọmọ-ọmọ Queen Victoria nghe ni Iyawo. Ọdun kẹta ti Ọba Jọji karun (George V.) de ori oye ni Ogun nla de, Ogun ajakaiye—ani, Ogun ti o d'ori gbogbo aiye k'odo-titi di oni-oloni. Ogun na pari, ni ọdun kẹwa, ṣugbọn rabọrabọ rẹ ko tan ni ilẹ.

Gẹgẹ bi ọpọlọpọ wa ti mọ alaiyeluwa Ilu Gẹsi nisisiyi ni Ọba karun ti oruko rẹ njẹ Jọji tabi George. Jọji kini, oloruko rẹ, ti ko gbọ ede Gẹsi rara jẹ Ọba Ilu Gẹsi lati ẹwa-lerugba ọdun titi di igba ọdun ti o kọja o din mẹta (1714-1277.) O jẹ Ọba fun ọdun mẹtala. Akiṣemọyin di Ọba Eko ni igbana.

Jọji, keji (George II.) gun ori oye, o si jẹ Ọba fun ọdun mẹtale-lọgbọn, (1727-1700.) O ku ni ọdun kẹrinle-lọgọjọ. Ko pẹ pupọ lẹhin ti Ọba yi bẹrẹ si jẹ Ọba, ni Akiṣemọyin ku, ti Ologunkutere si rọ ipo rẹ.

Jọji kẹta (George III.) Baba-baba Queen Victoria jẹ Ọba fun ọgọta ọdun, (1760-1820.) O ku ni ọdun kẹrinle-lọgọrun. Ọba Eko mẹta, Adele, Eṣilokun ati Idewu Ojulari li o si ba on nikanṣọṣọ li ori oye. Ni akoko Ọba Jọji kẹta yi, ni Ilu Amerika di ominira, ti o si bọ lọwọ Ijọba Gẹsi bi igbati abẹrẹ bọ li ọwọ adẹtẹ, ti o di ete, ti ọrọ ba ilẹ, ti o di ero.

Jọji kẹrin (George IV.) jẹ Ọba fun ọdun mẹwa, (1822-1830.) O ku ni ọdun kẹrinle-ladọrun. Ọba Oluwọle li o wa li ori oye li akoko na li Eko.

Lẹhin iku Jọji kẹrin yi, Ọba mẹta li o ti jẹ ni Ilu Gẹsi ki o to wa kan Jọji karun (King George V.) ẹniti o gba ade ni ọdun kẹtala, June 21st, 1911, ọjọ kanna gan ti Ọba Ọni Ile Ifẹ ti o wa li ori oye nisisiyi gba ade. Kabiyesi!

Jakejado Ilu Gẹsi, jakejado Ilu Nigeria ati gbo-gbo ibiti a ta asia Gẹsi si ni a ya ijarun si ọtọ bi ọjọ pataki, Ọjọ Ibi Ọba. Nitori na gbogbo ibi iṣẹ Ọba li o ti gbonin-gbonin; ṣugbọn anu awọn oṣiṣẹ ojumọ (Daily paid Employees) ti o nṣe iṣẹ li Okun, Apapa, Iddo, Ijọra, Ọgba Loko ati ni ibomiran ti nwọn fun ni isinmi l'aisi owo ṣe wa pupọ, nigbati o jẹ wipe owo awọn onisẹ oṣu (Monthly paid Staffs) ti a fun ni isinmi Ọjọ Ibi Ọba pẹlu ko ni din kọbọ kan li oṣu nitorina.

A gba a ni imọran, a si bẹ awọn Aṣoju wa, Members of the Legislative Council, ti o wa ni Igbimọ Ilu, ki ọ gbe wa lẹsẹ wipe ojokijọ ti Ijọba ba tun fun Ilu ni isinmi (Public Holidays) ki o ma ṣai san owo ọjọ isinmi na fun awọn oṣiṣẹ ojumọ (Daily paid Staffs,) nitori ipa ni owo awọn oṣiṣẹ ojumọ yi fi nto wọn jẹun li oṣoṣu, ko si yẹ ki a tun din owo diẹ kinun ti nwọn ngba yi ku nitori Holiday tabi Isinmi ti nwọn ko tọrọ li ọwọ Ijọba.

Ni iranti Ọjọ Ibi Ọba ni ijẹfa, awọn Ṣọja fi fere dabira li Ọdan; ọpọlọpọ enia li o si lọ wo iran na.

**Ọba Jọji karun ti a nyọ ayọ ọjọ ibi rẹ yi, ọpọ-lọpọ Oyinbo ni ko mọ ọ, bikoṣe aworan rẹ ti**

nwọn nri. Ọba yi lo gbọwọ lọwọ Oloye Oluwa, Ọba yi ni Herbert Macaulay ba sọrọ ni ilu Oyinbo lojukoju, nijelo iyẹsi na pọ gidigidi.

Nisisiyi, gbogbo wa lo mọ ọjọ ibi Ọba yi, ṣugbọn melo ninu wa lo mọ ọjọ ibi Ọba Alade Ọni Ile-ifẹ, Alafin Oyọ, Alake Abẹokuta, Oṣemọwe Ode Ondo, Ọwa Ilesha, Awujalẹ Ijẹbu Ode, ani Enia Dudu melo lo mọ ọjọ ibi Eleko, ọjọ Ọba Kano, Ọba Ṣokoto, Ọba Ado, Ọba Liberia ati Ọba wa miran. Nkan ti wa ko njọ wa loju rara, afi ti Oyinbo nikan ṣoṣo.

Adiẹ to ba tobi diẹ ẹdiẹ Oyinbo ni loju wa, ẹfọ to ba dara, ẹfo Oyinbo ni, ọgẹdẹ to ba tobi, ọgẹdẹ Oyinbo, ni, gbogbo nkan to ba sa ti dara ṣa, ti Oyinbo ni, Ọrọ majeṣi bayi pọ lẹnu awọn enia wa pupọ.

*God save the King.*

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## ỌGBẸNI EZEKIEL BANKỌLE DADA, ODIGBO OṢE.

***Mo yida, Emi ko ya ẹnu mi, nitoripe iwọ li o ṣe e.***

[ Lati ọwọ Ọmọ Awo ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Ojora kekere kọ lo mu ni nigbati a gbọ iku Ọgbẹni Ezekiel Bankọle Dada ẹniti o ku ni agogo meje alẹ ni ọjọ *Saturday* ti o kọja, *2nd June 1928* a si sin ni ọjọ Isinmi *3rd June 1928*. Iyọnu kekere kọ ni awọn ara rẹ ati awọn Ijọ Ereko ri ki wọn to le gbe oku rẹ lọ si Ṣọṣi Ereko lati lọ ṣe isin ikẹhin fun. Gẹgẹ bi a ti gbọ, Ọgbẹni Dada lọ si ibi iṣẹ lati ọjọ *Monday* titi o fi di ọjọ *Wednesday* ki o to ma le lọ mọ, ṣugbọn ki ilẹ ọjọ *Saturday* to su Ẹlẹmi ti gba, a sa ti kọ pe Ẹmi ni lati pada lọ sọdọ ẹniti o fi fun ni, ara erupẹ a si pada di erupẹ, ori wa wu pupọ nigbati a ri ajo ati iyonu ti awọn ara Ṣọṣi Ereko ṣe nipa oku yi, lati igbati wọn ti gbọ pe Ọgbẹni Dada di ologbe ni wọn ti ndoyi nibẹ titi wọn fi gbe lo, iru nkan bayi ko le salayi ma ri bẹ, nitoripe fun ọdun pupọ ni Ọgbẹni Dada fi jẹ Olukọni Agba awọn ọmọde ni Ṣukuru Ereko (*Day School*) on kanna yi si ni Iruju Ijọ Ereko, *leader* pataki tun ni ninu Ijọ Ereko ko duro ninu eyi nikan ani Oniwasu pataki ni (*Local Peacher*) mo ro pe, laisiyemeji ọpọlọpọ enia lo ma jẹri si pe, Ọgbẹni Dada ki nṣe ẹni kekere ninu Ijọ Ereko, iwasu rẹ, ati ọrọ iṣiri rẹ, yala ninu Ijọ ni o tabi ninu apejọ ni o kuro ni ẹgan ni hẹ, ani ṣẹ ko si ẹniti o ma wa ni abẹ iwasu Ọgbẹni Dada ti ko ni kan sara si pe ti Ọgbẹni Dada kuro ni ẹmọde nsere lori igi, ani ko ṣerọ, kini ka tun sọ ninu irchin Ọgbẹni Dada fun ilọsiwaju iṣẹ Ọlọrun, o fi agbara ṣiṣẹ, o fi ọgbọn ṣiṣẹ, o fi irin ṣiṣẹ o fi ọwọ, ṣiṣẹ o fi wiwo pe ki o bajẹ lagbara Ọlọrun siṣe Ogo Ọlọrun o mu mi ranti ọjọ kan ti mo ba pade nigba aiye rẹ, ani lakoko ti ẹsẹ nro Ṣọṣi Ereko, ti gbogbo rẹ di rudurudu, ti idanwo de si Ṣọṣi Ereko, ani lasiko ta pe Rev. Sagoe lọ sile, Dada fọwọ sọya pe lagbara Ọlọrun iṣẹ Ọlọrun ko ni bajẹ, ani o duro laiyeṣe, o fi ọwọ sọya pe ni ti pe Iwasu, ki wọn fi da on on le ma wasu lọsẹọsẹ, ti on ki o fi ikan pe meji, ani bẹni o ri, a ko gbọdọ ma to iyẹn lọ ti ti mọ njẹ nisisiyi, ẹnyin Ijọ Ereko tani yio gbe Jacob dide, nisisiyi, ọfọ nla lo tun ṣẹ nyin, ani opo nla kan lo tun ṣẹ ninu awọn opo Ṣọṣi Ereko, tani yio ha mu duro. Ẹ ma ranti pe, ọjọ ati akoko nlọ, ko si duro de ẹnikan, ko ba ṣepe Ọgbẹni Dada ti nṣe adonkiya sinu Ijọ tabi ayibikita ati wa si Ile Ọlọrun ni, ani kini enia yio ma sọ titi nisisiyi, a gbọ pe Ọgbẹni Dada ko fi Ile Ọlọrun rẹ ṣire titi o fi di ọjọ iku rẹ ani o si ti ṣe iwọn ti o le ṣe, o ku si ọwọ emi pẹlu rẹ, ani ṣẹ Dada lọ, ṣugbọn a ko le gbagbe iṣẹ rẹ lai larin Ijọ Ereko, kini ohun ti Ijọ Ereko le jẹ ti nwọn fi le gbagbe Dada larin wọn, ko si, awọn ọdọmọde ti nwọn nbere Imọran lọwọ rẹ lo ma gbagbe rẹ ni, tabi awọn agbalagba ẹgbẹ rẹ ti o nfi imọ ati oye balo, tabi awọn ọdọmọkuurin imiran ẹwẹ, ti Ọgbẹni Dada wa iṣẹ fun u ani wọn ni odigbati alaro maku kato mọ iye aṣọ ti orẹ, ko si ẹni kan ti o sọrọ Ọgbẹni Dada ni buburu ninu Ijọ Ereko, ijẹri si wa fun eyi nigbati a ri awọn gbajumọ nibi oku rẹ nijẹjọ, ori wa si tun wu nigbati a ri awọn ẹgbẹ Afunrugbin ti nwọn to ni meji meji siwaju oku rẹ titi fi de Itẹ ti nwọn si nkọ orin aro, o si tun wu ni lori pe, nigbati ojo nlanla kan bẹ silẹ, awọn wọnyi ko ṣa, bẹni wọn si tun kọrin titi wọn fi wọ itẹ ki awọn Alufa mẹta to wa sin ninu ojo na, Rev. A. N. Cole Sup. Tinubu Circult, Rev. M. O. Dada, Munister-in-charge Ereko Church Rev. T. J. Henry Munister-in-charge Ọbun-Eko Church, Awọn Ẹgbẹ Afurugbin wọnyi ko si sa, bẹni wọn si ko ri bọ inu ojo na de'le, eyi fi han ni iru enia ti Dada jẹ bẹ sini a ko le sọ ogunlọgọ awọn ọrẹ ati ojulumọ ti ojo wẹ de'le—nipa eyi mo gbadun yi o ẹnyin Ẹgbẹ Afunrugbin. Ẹ ku aṣeyẹ na, Oluwa ko mẹsẹ nyin duro, ifẹ na ti ẹni Oluwa na ko ni jẹ ko sa, bẹgẹgẹ lasi tun ki ẹnyin Ijọ pẹlu, ẹ ku ajalu na, pataki ẹnyin leader Ijọ Ereko, ati Alufa Dada, ati gbogbo Ijọ patapata lọkunrin ati lobinrin.

Mo yadi emi ko si le ya ẹnu mi nitoripe Iwọ li o ṣe. Mrs. Eugenia Ayọ Dada, gẹgẹ bi Iwọ papa ti mọ pe rere ni iṣẹ Oluwa ati pe Ọlọrun ki nṣe ibi fi gbogbo tirẹ le Ọlọrun lọwọ, On nikan na l'Ọba ti o ma ntu ẹru rẹ ninu yio si tu ọ ninu sa

gbękęle, gęgę bi Iwọ papa ti mọ pe enia ninu ijoko rere rę asan ni patapata mo ki ọ Eunice, Baba ko si mọ, şugbọn Baba wa Ọlọrun na si ni Baba gbogbo wa, maşe binu kọja bi ęniti ko ni ireti, nitoripe Ọlọrun mbę loke yio si şe Baba fun ọ. Duao ti Oluwa, a tun ki nyin gbogbo ęnyin ara ati ębi Ọgbęni Dada, Ezekiel lo, ko si wo ehin, ki o tọ nyin wa mọ, ęnyin ni yio tọ lọ, ohun gbogbo ko sęhin Ọlọrun, bi o ma si ti wun ni o nşe Işę rę, ko si ęniti iku Ọgbęni Dada ko dun, lọkunrin ati lobinrin, ninu Ijọ, larin ębi, nibi işę ladugbo ati larin awọn ęgbę rę, jugbo rę lọ awa si gbagbọ pe bi eyi ko şe, boya eyi ti ko ba şe iba ju eyi lọ, iku ya ju ęsin lọ ęnyin ara. Ę ranti pe aiye yi ki nşe Ile wa, bo pę titi, tulasi a o ku, ka ku lọmọde ko yęni san ju ka dagba oşi lọ, awa gba pe bi o ti wun Oluwa lo şe işę rę, bi o si ti yę laiye yi o dani loju pe, bę gęgę ni yio yę lọrun ohun to ku fun emi ati irę ni pe ka mura lati lọ fi ayọ ba lọhun. Pęlu iwa rere gęgę bi tirę.

Ę o ri bi Oluwa ti ma nşe işę rę, Ọgbęni Dada ni ęniti orukọ rę wa lati wasu ni owurọ ọla ni Şọşi Ereko, şugbọn Ọlọrun ni, On gan ni ęniti a o sọrọ rę ni ọjọ na, Oluwa nikan lo mọ ọjọ ti a o ku, tani le sọ ni ọjọ ti nwọn şe *Plain* yęn pe Dada yio di ologbe ki akoko na to to, tabi ni ijędogun ti Dada wa si Şọşi ti o ba wọn şe isin pọ, tani mọ pe ọjọ isinmi ti o ma tęle ko ni ba lorilę, bę gęgę laiye ri, anu şe ni pe, a ko le sọ pupọ ninu itan Ọgbeni Dada nitoripe a mọ iba wa nigbati o de Ijọ Ereko ni ọdun 1901. Şugbọn mo rope ę o gbo pupo ninu itan rę lọla lęnu awọn Agbalagba ni Şọşi Ereko. Ti a ba ni ki a ma sọ iwa tabi işesi Ọgbęni Dada, a ko rope a le dakę nitorina ę ję ki a fi gbogbo tiwa le Ọlọrun lọwọ nitoripe On lo şe e.

Dada, ma sun ko si ma simi
Gbori rę le aiya Olugbala rę
A fę, şugbọn Jesu fę ọ ju,
Sunre, sunre, sunre.

---

## NWỌN NGE NYIN LỌWỌ, Ę NBỌ, ORUKA.

### Apa Keta.

Nigbati iwa panşaga yi ba bo ęlomiran loju tan, o nmu wọn kọ ọkọ silę, lati le wa ni ominira arawọn fun lati ri aye lati ma şe bi o ti wn wọn kiri ilu, iwa wọnyi ko ha nsọ wọn di oloriburuku ani ko ha nsọ wọn di ęlęmi kukuru baun? Eyiti iwa yi ba si bo loju tan patapata ki ijęki nwọn gbọ ti ọko wọn nile mọ, bęni nwọn ko si ni fi ọkọ na silę, bi ọkọ wọn ba ni iwọ ko gbọdọ lọ si ibikibi nwọn a ni jaguda pali, awọn kole şe ki awọn ma jade, nigbati awọn ko gba ęlęha, bi nwọn ba bati nwọn a ni awọn kole şe alai de ile awọn arara— alalikuwa iya tabi baba wọn ma ti kilọ fun wọn pe awọn ko gbọdọ saba lati ma ri wọn ni ile awọn nitoripe ile ọkọ ni obinrin ngbe, eyiti, o ba si nbęru ọkọ rę die a ma yọ ọdę ayọta, ti ọkọ rę ba ti mu ọna oko-aru rę pọn ti awọn mejeji ma fi şe ọmọ enia, awọn a wa a şi nwọn a fi ori le ọna igboro pę-pę, ni nwọn ma to gbogbo rę lọ bi o ba to aseko ti ọkọ wọn ma şiwọ wa'le nibi işę, awọn a ti yara sure wa'le, nwọn mọ agogo ju ęniti o nyin agba ni Apapa lọ.

Bi ọkọ wọn na ba si gba owo nibi işę ni ipari oşu, bi o ba jafara lati fun won ni owo onję, nişe ni nwọn a ma fi igi imu sunkun kiri ile bi ęlęgbara, pe okọ mi ko tọju mi, obinrin ti o si nhu irufę awọn iwa ti a nwi wọnyi ha ni ero rere si ọkọ rę bi? Nigbana ni iwọ yio ma gbọ wipe ale ni ọkọ mi nfi owo rę yan, o wa ję wipe atete k'ole, ole nki oloko.

Awọn omiran ęwę si mbę ninu wọn ti ko bikita pe ọkọ on fi owo onję silę, ko fi owo onję silę, panyanun ni nwọn a ma huwa ti ọko wọn yio fi le kọ wọn silę, eyiti ọkọ rę ba si jaja fi ọwọ ara rę le jade; adura rę gba ni iyęn, yio wa duro wọnle, a gbe ogun iwa agbere rę kari ni papa julọ.

O ni iye igba ti a nri ọrọ nipa iwakuwa lori iwa agbere ti a nwi yi ka ninu iwe irohin, sibęsibę nwọn fi owu elepo owu oşi wọn di eti.

Bi o ti wa ni liki bę lo wa ni ghanja, mo yan ti awọn ọkunrin niba fęrę şiwaju nisislyi, bi o ti wa fun ọbinrin be lo wa ni ara ọkunrin, bi awọn obinrin ti ni iwa buburu yi lọwọ, bę lo mbę lęsę ọkunrin papa, ti awọn ọkunrin tilę buru o kọ adię lęsę, ọpọlọpọ won lo ti yọ si ọrun apapadodo nipa iwa agbere wọn, ti a ro wipe aseko ọjọ wọn lo to, iru awọn ęniti o nku bayi ha wa nipo ęniti a le ma daro lọ titi aiye.

Bi ọpọlọpę ęlomiran ti nfa rę leti nipa iwa rederede yi bęni ęlomiran wa ti ko bikita lati ma şe ikilọ fun awọn ọmọ wọn, bi nwọn tilę ri wọn ti nwọn nhuwa janduku bayi kiri, nwọn a fi riri şe alai ri, bi a tilę ri ęlomiran ti o lọ sọ fun wọn wipe o ko fa ọmọ rę leti, iwa ti o ma nhu yi ko ma yę "ọmọluwabi" nwọn a fi gbigbọ şe alaigbọ, nwọn a fi ọmọ wọn sọfa si ilu lati ma şişę owo wa fun wọn ni ile, ninu owo ęlębi ati alare ti nwọn ba nrigba ni awọn obi miran yio ma gba lọwọ wọn lati ma fi gbọ bukata, ogo ni irufę awọn ọmọ bę ko ha ni ya poki si ilu.

(*Koi pari*)

ỌMỌ-ILU.


Disinfectant Soap of
Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home— it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap
Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

# JUST ARRIVED.

Glaxo (*large and small*) 7/6 & 4/6
Gripe Water 1/6
Saccharine 1/-, 1/6
Lactogen 2/6
Kalzana 6/-
Anti-Rhumatic Salt 2/6, and 3/6
Rheumatism Pills 1/6
Yaro (*small and large*) 2/3 & 3/3
Dr. Pierce's Pleasant Pellet 1/6
Pile Pills 1/6
Pile Remedy 7/6
" Ointment 2/6
etc., etc., etc.

Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae for general Debility, shaking of the hands and limbs, dimness of sight &c., miraculous curer, largest size £2 2 0.

Vibrona the Ideal Tonic Wine for lovers of good health 7/6. *Postage extra.*

APPLY TO:—

# Iyin Oluwa Medicine Stores

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
22, Agarawu Street,
109, Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH ).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

ẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*( A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

***Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.***

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———— :o: ————

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.